# IDAJO NJEMANZE, ENIA MERIN JEBI IKU



AWOGBA
Omode fun Girl, Eyi, Hibu-ehin, Orere, Ra Tire Ni Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare Okebola, Ibadan.
116, Great Bridge St., LAGOS

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C.
SERVES
YOU
WELL

VOL. VIII No. 462. ELETI - OFẸ LAGOS, SATURDAY, APRIL 7, 1956. KOBO MEJI (2d.)

## Idajo Njemanze Enia Merin l'ojebi Iku

Ni ọjọ Thursday ti işe ọjọ karun Oşu yi ni Kotu ti adajọ mẹta şe idajọ lori ẹjọ arotunro, ẹjọ kotẹmilọrun ti awọn enia mẹfa ti Idajọ Kotu Ganran da lẹbi iku lori ọrọ ẹjọ iku akọrin olohun'yọ Israel Njemanze ti awọn ri oku rẹ ti wọn ge si wẹwẹ ni oju Irin Reluwe ni iyanọ Surulere ninu ọdun 1954, ọdun kẹta s'ẹhin.

Idajọ Kotu adajọ mẹta da awọn enia meji silẹ, ki wọn ma lọ ni alafia, awọn enia mẹrin ti o ku ni Kotu adajọ mẹta da l'ẹbi iku. Awọn enia meji ti Kotu nla da silẹ ninu awọn ọdaran na ni Lawal Dada, ati Dada Owolabi.

Awọn enia mẹrin yoku ni Samuel Jẹgẹdẹ, Michael Adeyẹmọ Cyril Anikwe ati Peter Nwangwu, awọn ni yio nilati lọ ku iku oro iyẹgi-mọlẹẹ pa.

Lẹhin Idajọ yi ni Lawal Dada ọkan ninu awọn meji ti Kotu dasilẹ sọ wipe:- "Modupẹ lọwọ Ọlọrun ngo tun pada s'ẹnu işẹ mi ni Orthopaedic Hospital, bi ala ni o ri l'oju mi" Dada Owolabi ti işe ẹnikeji ti Kotu desilẹ sọ wipe on yio tun lọ bẹrẹ işẹ ẹmu dida ti on ti nta tẹlẹ.

Jẹgẹdẹ a bo sun ni, orun kẹ, niwaju adajọ!

VOMICURE




Egbogi atata fun obinrin ti o mbi ninu oyun, ti ko le jẹun daradara, ti isalẹ ikun rẹ ba ndun ati gbogbo aisan to ma nyọ aboyun l'ẹnu.

Kosi ewu fun lilo rẹ, şa ra igo kan ki o si ma gbadun alafia ara rẹ.

O wa ni Şọbu:-
EJIWUNMI MED. STORE
LAGOS.
ati awọn Şọbu Egbogi Kakiri.



Samuel Jegede



DADA OWOLABI (Freed man)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onişowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nşe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IŞẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AŞOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

Blackpod
Capsid

Ki o le pa'no arun ara igi Koko wonyi, Ma lo:--
ẸRỌ TI A FI NFỌN EGBOGI SARA IGI KOKO

Mysto Spraying Equipment



Eyiti oni On'ẹ MYSTO MODEL NO. 159
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba, ẹrọ l'o nfọn omi rẹ,

Eyiti oni Ontẹ "UNAMYST"
Galọnu mẹta ni omi egbogi to ngba, ọwọ ni a fi nyi ẹrọ ti o nfọn omi inu rẹ.

A le ri awọn Irin - Işẹ rẹ ra ti o ba bajẹ ni owo pọku.
Fi ẹrọ wonyi lo:-

Egbogi ti a npe ni "PERENOX" ati "PEREPOD" fun arun Adu.

Lo "DIDIMAC" 25 fun arun kokoro miran to nba Koko jẹ
Ó wa ni gbogbo ẹka Şọbu.

The United Africa Co. of Nigeria Ltd
ati U. A. C, (TECHNICAL) LTD.



Aworan inu iwe wa yi niti awọn enia ti awọn ọlọpa kọkọ mu fun ẹsun iku Israel Njemanze ki adajọ kotu kekere to da ninu wọn silẹ. Agbaregbabọ, enia mẹfa ni o ku l'enu ẹjọ na ti nwọn nṣe ni ile ẹjọ aro-tunro kotu kotẹmilọrun nisisiyi.

## Ejo Kotemilorun Bere Nile Ejo

Ọrọ ẹjọ aro-tunro lori iku akọrin olohu nyọ Israel Nwaoba Njemanze ti nwọn ri oku rẹ ri oju irin ọkọ-ilẹ (Railway) ni iyanọ Surulere ni ọjọ kan ninu oṣu April ti ọdun tokọja ti bẹrẹ ni Kotu Kotẹmilọrun ti ilu Eko.

Awọn enia mẹfa ti Kotu da lebi iku lori iku Njemanze na ni Peter Nwangwu, Cyril Aniekwe, Lawal Dada, Dada Owolabi, Michael Adeyẹmọ, ati Samuel Jẹgẹde. Awọn adajọ ti o ngbọ ọrọ ẹjọ wọn na ni adajọ agba, Sir Foster Sutton, O. Jibowu ati M. J Abott.

Boya idajọ na le bosi ni ọjọ Saturday oni, bi nwọn ba ti da ẹjọ wọn na si ni a o rohin rẹ ni ẹkunrẹrẹ fun yin ni ọsẹ to mbọ l'agbara Edumare.



Israel Nwaoba Njemanze

## Kini Idi Irin Ajo Yi ?

IBADAN— Eyiyi ni ibere ti o tọ ki c wa ye nipa irin ajo Oloye Awolọwọ ati awọn janma ti wọn nrin orilẹ ede Europe, America ati Asia yika nisisiyi fun anfani ati mu idẹra ati Igbega owo ba Ipinlẹ yi.

Laipẹ yi ni Ijọba fi aṣẹ si gbogbo ipinnu ti o wa ninu Iwe ti a npe ni „Eto Ilọsiwaju fun Ipinlẹ Iwọ Orun fun 1955 titi di 1960" a si tun nda pe ni Eto ọdun marun" Iwe na ni o fi han ni ni ki'kun awọn awọn ireti ati agbọkanle to wa li ọna owo ṣiṣe ati idasẹsilẹ fun ọdun ma'un gbako a si ti pin iwe na kakiri gbogbo ibi ti awọn ero irin ajo yi yio de Ninu irin ajo yi wọn yio fi ye awọn to le ṣe iranlọwọ fun wa gẹgẹbi awa na ti gbaradi to lati lo gbogbo ọgbọn owo ati ipa wa fun ọnakọna ti o le mu anfani ba ipinlẹ yi, a si gba pe wọn yio ba oluręre awọn oniṣe ati onisowo awọn ilu wọnyi pade.

O si jẹ ohun iwuri ati idunnu pe lati ọjọ ti wọn ti lọ gbogbo irohin to nkan ni jẹ rere tobẹ gẹ ti a tun ni lati tun fi awọn Ọgbẹni O Batẹyẹ W.B. Dawodu ati S.A Ogunwale ranṣẹ si wọn lati tubọ mu eto to.

## Ijoba Egba Ndabira

Ijọba Ẹgba ti pinnu lati kọ ọmọ merin ni iwe ọfẹ ni ile Ẹkọ giga ni Abẹokuta ọmọkunrin mẹta ni Abeokuta Grammar School ọmọbinrin kan ni Abẹokuta Anglican Girls School.

Igbimọ Ijọba yi na ti yọnda ẹgbẹdogun pọun lati fi tun ilu Abẹokuta ṣe (Abẹkuta Town Planning) Igbimọ yio ma tun yọnda ilẹ ni Kemta fun Federal Government lati kọ ile Ẹrọ Gbohunto nṣiṣẹ funrarẹ ati Ile Ifiwe ranṣẹ ( a join Automatic Exchange and Post Office.)

Igbimọ yi na tun pinnu pe awọn yio bere aṣẹ lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati le ma yan obinrin sinu igbimọ atunluṣe yika gbogbo ipinlẹ Abẹokuta.

**ỌGBẸNI J.I.C. TAYLOR DI ADAJỌ IWỌ-ORUN**

IBADAN -Ọgbẹni Taylor ti a bi ni oṣu kẹjọ ọdun 1917 kọ ẹkọ rẹ ni ilu Oyinbo, o si gba ọpọlọpọ oye ti Brasenose College Oxford ni 1940, ati oye iyi fun ẹṣẹ jija.

O wọ inu iṣẹ awọn amọfin ni 1940, lati igba na lo si ti nba iṣẹ yi bọ ni Nigeria ko si si tabitabi, ẹnikẹni mọpe o jafara pupọ ninu ofin.

NO. 73/S.2/vol VI/86.
**Department of Information Services**
WESTERN NIGERIA
VACANCY FOR POSTS OF ASSISTANT PUBLICITY OFFICERS
Applications are invited for suitably qualified candidates for appointment as Assistant Publicity Officers in the Department of Information Services, Ibadan.
Salary Scale:- D.3; £270 x 12 – 360.
For full particulars see Western Region Notice No. 183 of the Western Region of Nigeria Gazette No. 15, Vol. 5 of 22nd March, 1956.
Closing date 7th April, 1956.

62.

**NOTICE**

Applications are invited for the post of Second and Third Class Laboratory Technical Assistant, Education Department. Particulars in Government Notice No. 545 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 29th March. Applications to Chief Federal Adviser on Education, Federal Education Office, Lagos.

Closing date 30th April.

## Irora Ehin Didun

Ọna wosan rẹ niyi.

Njẹ o mọ wipe Kidinrin lo njẹ ki ẹhin ma dun enia? Bi ko ba si ailera fun nibẹ gbogbo idọti ara ni yio ma ṣẹ danù Ṣugbiọn bi nwọn bo nṣe tikọtikọ idọti ara ti o nwọjọ pọ a ma jẹki ẹhin-dun ni.

Aṣe egbogi DE WITT'S PILLS yi lati jẹki Kidinrin ṣiṣẹ. Iṣẹ ti a ṣe egbogi yi fun gan niyẹn, yio wo wọn san tan, yio si mu alafia wa fun oluwa rẹ.



O to iwọn adọta ọdun ti egbogi yi ti nṣe iwosan fun enia ti Ẹhin nro. Aimọye iwe ọpẹ ni a ti ri gba kakiri aiye. Lọ ra tirẹ ni ṣobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos

## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS
AND
NEW COURT ROAD,
IBADAN

### EYIYI MA ṢE KELEBỌ O ARA OGBOMỌṢỌ

Lọna ọjọ mẹta yi, ni awọn ara ilu Ogbomọshọ ake bosi wipe, awọn nfẹ ki ibusọ ibiti awọn Mọto ti o nko ẹru, ati ero ma gunlẹ si arin ilu Ogbomọṣọ nitori ki o le din irin awọn ero ti o ngunlẹ si Ogbomọṣọ ti o nlọ si Igboro ku. Ṣamọ-ṣamọ ri Taki ibiti moto ti ngunlẹ si tẹlẹ-tẹlẹ tẹlẹri, arin ilu Ogbomọṣọ ni ibẹ jẹ, ki wa ni lala-koko fẹfẹ ti nwọn nkigbe si ijọba lati ṣe ibusọ mọto miran. Kini tun le fa inu-wo rẹpẹtẹ yi wa?

Ibusọ titun na ti a ti ṣe, ti a si ti pari, lati esi wa, koiti jẹ lilo titi di oni.

## Kinişe ti inu awọn Ẹbi Ogbe* fi ma a ndun!






EBI Ogbe ngbadun OVALTINE lojojumọ. Eyi ni afikun onjẹ to nfun wọn ni ilera. Bi enia ba fi OVALTINE ṣe onjẹ arọ yio fun u ni agbara ati okun ti yio le fi ṣe iṣẹ ojọ. Ti o ba mu lale yio fun o ni agbara ti oti lo sẹhin pada, yio si tun fun ni ilera, ọkan rẹ asi fuye, wa si sun gbadun. Fi OVALTINE kora ni mimu wa si ma a gbadun!

** Ọgbẹni ati Iyafin Ogbe ati awọn ọmọ wọn gba ẹbun idije ti awọn apapọ Ẹgbẹ kede ninu "Sunday Times" f'awọn ẹbi ti nwọn ni ayọ fun ilera ju.*

**OVALTINE**



–ko si ohun ti o dara to!

OWA 188y

# ẸLẸTI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos — "ELETI - OFE LAGOS"
P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. VIII. NO. 462, LAGOS, SATURDAY APRIL. 7, 1956.



## Ise ()wo Ni Tabi Ise Pamba?

Irohin kobakungbe kan ti a gbọ nipa awọn enia wa ti nwọn mba iṣẹ onjẹ ojọ wọn lọ silu Fernando-Po jẹ eyiti enia ko le ni ero wipe irufẹ iṣẹlẹ bẹ ṣile ma ṣẹlẹ ni ilu ti Aṣoju Ijọba Gẹsi ba gbe wa.

Gẹgẹbi a ti tẹ si apakan iwe Irohin wa ọsẹ yi, gbogbo iwa ati ilo t.ni ma mumi ti awọn agbanisiṣẹ ni abẹ Ijọba General Franco fi nlo awọn enia Nigeria ti wọn ko lọ ṣiṣẹ lọhun, bi iwa ki a lu ọmọ enia bi ẹniti Ọlọrun kọ lo ṣ'ẹda rẹ, tabi ki a ko wọn da s'ẹwọn lori ifura lasan, ọrọ ti ko nidi, mu ki a fi wos'ka wa ọsẹ yi ke si Ijọba apapọ (The Federal Government) tiwa nihin fun iranlọwọ idabobo fun awọn enia Nigeria to ba iṣẹ onjẹ ojọ wọn lọ silu awọn ọdaju enia ti nwọn np= ni Fernando Po.

A DUPẸ FUN IJỌBA WA

Gẹgẹbi Ijọba wa ti ṣe ikede wipe awọn ti bẹrẹ si ṣe iwadi nipa irohin ti Ọgbẹni J. I. Pepple oniṣẹ iwe Irohin ti awọn Iwe Irohin wa nilu Eko nihin tẹ jade wipe wọn ti da Ọgbẹni na silẹ, ati pe ylo si pada de silẹ yi laipẹ, jẹ ohun to dun mọ wa ninu gidigidi. A si ni ireti wipe Ijọba wa ko ni sinmi, bẹni wọn ke ni baye titi ti wọn o fi ri idi ti awọn enia mẹtadinlogun ti wọn ko da s'ẹwọn gẹgẹbi iwe ti Ọgbẹni oniṣe Iwe Irohin na kọ ranṣẹ lati inu ọgba ẹwọn ni Fernando Po ti awọn Iwe Irohin tẹ jade.

A bẹ Ijọba wa, papa Alabojuto iṣẹ (Minister of Labour) ki wọn ba wa fi opin si iwa hauka, iwa aikolanu ẹda enia ẹlẹgbẹ wọn ti awọn agbanisiṣẹ ti ilu Fernando Po ma fi nṣe iwa hu si awọn enia Nigeria ti o ba iṣẹ lọ si ilẹ wọn. Ọba l'o ngba alai lara o.

## Rogbodiyan Ija Nilu Kano

Rogbodiyan ija ti o bẹ silẹ ni Satide ọsẹ to kọja sọ enia mẹ'alelẹdọrun (93) di ẹlẹwọn ninu awọn ẹgbẹ N.E.P.U to ba ọlọpa ibilẹ ja nigbati wọn ṣe idajọ le awọn onija na lori ni Kotu Alikali, Kotu Ibilẹ ti ilu Kano.

Idajọ na bẹrẹ lati ọdun marun to fi de oṣu mẹfa ati awọn bi ogun enia ti nwọn so agbejẹ mọ nidi wipe wọn ko gbọdọ ṣe ijọngbọn mọ.



## IMORAN FUN EYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ e wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)
O wa Lọdọ :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS



## MINISTRY OF EDUCATION
### WESTERN REGION.

NOTICE TO ALL PARENT IN WESTERN REGION

**Registration of Children for Primary one in January 1957**

The Registration period for children eligible to enter Primary One in January next year will commence on Monday 7th May, and end on Friday, 3rd August.

2. Each of the 7,000 existing Primary Schools in the Western Region will constitute a Registration Centre.

3. Children must be registered during school hours at a school within a radius of three miles of their place of residence.

4. Only children who will have attained the age of 6 years in January, 1957 and who will not have reached the age of 7 years, should be registered.

5. The provision of Primary One educational facilities by the Western Regional Government will be restricted next year to those children who have been duly registered as instructed above.

6. Parents are therefore warned that their failure to have eligible children registered during the official period (7th May - 3rd August) may mean that non-registered children who present themselves in January, 1957, will be refused entry to Primary School.

7. The extensive planning involved in providing the extra classroom accommodation required each January in based on the preceding mid-year registration returns.

8. The vast expansion of Primary School facilities throughout the Western Region commenced in 1953 and is now well know to every parent.

9. Government is therefore no longer prepared to entertain the provision of a late supplementary construction programme, made necessary by the negligence of parents in not availing themselves of the facilities provided by the 3-months registration period.

10. The headmasters and staffs of all Primary Schools in the Western Region are asked to assist in ensuring that the above details regarding registration are fully understood by the parents in their areas.



Mo Gbadun Siga Pirate



## Idawo Fun Agbakaiye Ere Olympic Fun Ọdun 1956

IBADAN - Ki awọn elere wa ni orişirişi ọna ba le ni anfani lati ba awọn elere ti gbogbo agbaiye pejọ ni ọdun yi ni melborne Australia ao ya ọsẹ kan lati ọjọ kọkanlelọgbọn oşu kẹta titi di ọjọ keje oşu kẹrin ọdun yi sọtọ fun ati tọrọ owo fun ati le ran awọn ọmọ wa lọ.

Yio jẹ ohun idunnu pupọ bi gbogbo wa lọkunrin-lobinrin, tọmọde-tagba ba le sapa wa fun idawo yi. Idi rẹ ni pe ipinlẹ iwọ orun pin aye to ga pupọ larin awọn to şe daradara ni ere Olympic ti a ti şe sẹhin, ati lorişirişi ere ti wọn ti tun şe laipẹ yi, awọn ọmọ ipinlẹ yi lọkunrin lobinrin lo gbori, nitorina ohun ẹyẹ ati iyi ni pe ki a tubọ fi owo wa şe iranlọwọ fun ilọsiwaju wọn ati igbega ilẹ wa.

Ọdọ Ọgbẹni J.A. Adebiyi National Bank of Nigeria Ltd, Ibadan ni ki a fi gbogbo itọrọ wa ranşẹ si, ao si fun wa ni iwe morigba fun gbogbo owo, gbogbo awọn to ba si da owo ni orukọ wọn yio han ninu iwe irohin.

Oluwa fẹ oninudidun ọlọrẹ nitorina ẹ şe bi Oluwa ba ti fun yin lagbara to fun ogo ilu wa, Ọlorun yio si ran yin lọwọ Amin.

## Gomina Yio Be Abeokuta Wo

ABẸOKUTA— Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun, Sir John Rankine, K.C.M.G., K.C.V.O. yio bẹ Ipinlẹ Abẹokuta lati ọjọ kẹrin oşu kẹrin ọdun yi. Oludamọran Ijọba Ibilẹ I.F W. scholfield pẹlu igbakeji rẹ Ọgbẹni E.W. Pratt yio pade rẹ ni Ilugun ni ọjọ na. Ọba Alaiyeluwa Alake ati awọn Ọba Ẹgba yoku yio kesi Gomina ni Oke Igbẹin ni agogo mej'la kọja işẹjumẹdogun ni ọjọ na. Ni agogo kan abọ ijọ na, Gomina yio jẹun pẹlu Alake ni afin rẹ, ti o ba si di agogo marun ijọ na, Gomina yio gba ere ohun işire afigigba (Tennis) ni Abẹokuta sports Club. Ti o ba di ọjọ karun oşu kẹrin ọdun yi, Gomina yio ba Igbimọ gbogbo Ẹgba pejọ pọ, yio si bẹ Nyangao Barracks ati Officer Mess ti 2nd Battalion Queens Own Nigeria Regiment wo ti o ba di agogo marun irọlẹ ọjọ na, yio tun gba Tennis ni Abẹokuta Recreation Centre

Ni ọjọ kẹfa oşu kanna ni yio bẹ St. Leo's Teachers Training Centre, St. Paul's Teachers' Training Centre ati Ẹgba Divisional Farm Centre ati dam wo.

Ni ọjọ keje oşu kanna, Gomina yio lọ si Iboro ati Mẹkọ Agricultural stations ni ọjọ kẹjọ oşu na lati lọ bẹ awọn aguntan ati akurọ Cocoa wo.

Ni ọjọ kẹsan oşu kanna yio ba gbogbo Igbimọ Ẹgbado pejọ ni Ilaro, yio si tun bẹ Ẹgbado College wo. Ni ọjọ kẹwa yio bẹ akurọ ti Igbogila ati ti Igan Alade wo, yio si pada si Abẹokuta ni agogo kan ọjọ na, to ba si di alẹ yio pada si Ibadan.

**Polowo Qja Re**

**Sinu Iwe Irohin**

**Eleti-Ofe**

61.

## NOTICE

Applications are invited for the post of Education Officers, King's College, Lagos. Particulars in Government Notice No. 506 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 22nd March. Applications to Secretary, Federal Public Service Commission, Private Bag No. 2586, Lagos. Closing date 30th April.

**Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials**

PLEASE CONSULT :

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.
The house where Courtesy & Satisfation are Guaranteed

**AKIYESI PATAKI**

**Bi o ba fe ra Eleti-Ofe tabi o fe polowo oja sinu re,**

LQ SI:-

**18, Race Course Road,**
OKE—PADI, IBADAN.

E mu irohin wa tabi ohun to ba je edun ckan yin, ki e si ma ka Iwe ELETI—Ofe nigba gbogbo.

YOUR ENGINE MAY BE MORE POWERFUL THAN YOU THINK!

I.C.A. UNLOCKS ALL THE POWER IN YOUR ENGINE.

Only SHELL has I.C.A

IGNITION CONTROL ADDITIVE
(incorporating tricresyl phosphate)

THE MOST POWERFUL MOTOR SPIRIT YOU CAN BUY

# Itan Bi Osugbo Ti Se De Ilu Eko (Apa II)

Lati Ọwọ Ẹsọ Ikoyi

Ni Abẹokuta, ko si Awo Oşugbo, ẹnikẹni ti o ba jẹ ọmọ Awo Oşugbo, Ogboni, ni nwọn npe, Ohun ti nwọn si npe ni Ogboni ni Ẹdan ti nwọn ngbe dani gẹgẹbi ọpa

Awo Osuogbo yi ni awọn ara Eko fi nşelu, bi ẹnikan ba şẹşẹ darukọ Oşuogbo, nşe ni nwọn o yara fọwọ bo o lẹnu tabi ki nwọn tuka. Nitoripe ọpọ awọn enia ti nwọn puro mọ wipe, nwọn bu Ọba tabi iioye, Ọba yio ranşẹ si wipe bi o ba jẹ wipe ko bu Ọba nitotọ, ki o wa lọ bura loju Osuogbo lọna Işẹri. Şugbọn ko si ẹniti o lọ ti o si pada bọ ri, ayafi Ikuşigbagbe ti o pada di Apena.

Lati akoko igba aiye Ikuşigbagbe yi ni nwọn ti bẹrẹ si fi Awo Oşugbo şelu Orişirişi awo lo mbẹ nilu Eko bi awo Ọpa awo Erikina awo Akala awo Alarogbo awo Olokun awo Oro ati awo Oşugbo. Awọn Arọkin sọ wipe Ogbẹni Alagba Alufa ẹni ọwọ T. A. J. Ogunbiyi jẹ ọkan ninu awọn Ologboni ti ilu Abẹokuta. Nigbati o di ọdun 1920 ni Alufa yi bẹrẹ si tan ihinrere kalẹ nipa awo Oşugbo o si da ẹgbẹ kan silẹ ti a npe ni Ẹgbẹ Awo Oşugbo ti a da silẹ lọtun (R. O. F.)

Awọn ẹgbẹ titun yi ka ilosi ari işesi awọn Oşuogbo ati Oşugbo ti o ti wa si wipe nwọn jẹ ti Keferi. Dipo oju ibura tabi ọmọnihorogbo Bibeli ni nwọn fi bura eyi nikan ni nwọn yi pada gbogbo iyoku bi ẹnọ apẹrẹ tabi isami imura ati itagbe gbogbo rẹ ni awọn faramọ

Ninu ẹgbẹ R.O.F. o fẹrẹ jẹ wipe ẹsẹ awọn gbajumọ ati Bọrọkini ilu lo pe nibẹ. Pẹlu pẹlu ẹniti ko si ninu awo Oşugbo R.O.F. yio soro fun oluwa rẹ ki o to le ni ilọsiwaju nibi Işẹ gbogbo awo nwọnyi lo panupọ fi ẹnu şọkan wipe, ohun ti ẹgbẹ R.O.F. ba şe ni awọn şe gẹgẹbi ẹgbẹ Awo Babalawo, ẹgbẹ awo Işegun ẹgbẹ Eleşu, ẹgbẹ Onibantẹ, Awo Ọpa, Awo Erikina, Awo Akala, Awo Olokun, Awo Alarogbo, ati awo Ọta ati Ẹlẹgbara.

## AWỌN ẸGBẸ W. H. O. WA IDI ABAJỌ RI

BRAZZAVILLE. Irohin kan wa wipe awọn agbajọ ẹgbẹ Onişegun Oyibo ti a darukọ soke yi, ti de si ilẹ Nigeria. Ohun ti nwọn kọkọ şe iwadi ni wipe ẹsẹ ti ilẹ Nigesia gboro to yi, şugbọn ti awọn enia inu rẹ ko to nkan.

Nigbati nwọn wadi lọ, ti nwọn wadi bọ, nwọn sọ wipe Koko Iru, ati Gbọnringbọn ni o fa a. Nitoripe nibiti awọn ẹran bi Malu Agutan, Ewurẹ ba gbe pọ si, nibẹ ni awọn kokoro na ma npọ. Ibiti awọn kokoro na ba si pọ si, ẹda enia ko ni le gbe ibẹ. Nipataki, kokoro yi lo nle awọn ada-ẹran jẹ bi gbari ati Fulani ti nwọn ti nlọ lati ibi kan si ekeji.

Igbo yanmu-yanmu ati nke kiri wipe on lo nfa arun Iba Pọnju-Pọnju (yellow Fever) Nisisiyi arun yi ko si mọ Ọlọrun ti gba agbara rẹ o ku awọn ti inu igbẹ. Şugbọn Iru ati Gbọnringbọn ko fun wọn laye lati ba tun igbẹ jẹ, iru awọn kokoro ba wọnyi ni awọn ẹgbẹ W. H. O. fẹ gbe oju ija si lalpẹ yi.

## IJỌBA TI MU OFIN MAŞẸ ỌTI KURO

Ninu iwe ijọba Gazette No. 15, Vol 5 ti ọjọ 22nd oşu March 1956, Gbogbo awọn ofin ti nwọn ti şe wipe enia ko gbọdọ şe ọti Bọlugi tabi Oyinbogọ mọ ni ijọba ti mu kuro, ẹnikẹni si ni anfani lati şe ọti na nisisiyi laisi ewu nilẹ Yoruba.

Awọn ara ilẹ Kukuruku, ilẹ Isan apa kan ilẹ Asaba leti odo Ọya ati ni eti odo Amambra nilẹ Onitsha ni bi ti ofin ti wa pe ẹnikẹni ko gbọdọ mu ọti, aye ti şi silẹ fun wọn nisisiyi, ẹnikẹni ti o ba fẹ le mu ọti.

Ati ni agbegbe ilẹ Ibini, Ondo, Warri, apakan ilẹ Abẹokuta Ijẹbu Ode, nibiti nwọn ko gbọdọ fi ẹnu kan ọti tẹlẹ ri Ijọba Iwọ Orun ti fun wọn laşẹ lati ma mu ọti bi wọn ti fẹ.

## MINISTRY OF EDUCATION WESTERN RIGION.

### ADMINISTRATION OF SCHOLARSHIPS AWARDED BY THE WESTERN REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.

It is notified for the information of all concerned that the responsibility of administering the Western Regional Production Development Board scholarship scheme has now been transferred from the Board to the Ministry of Education, Western Region. All scholarships already awarded and any further awards which may be made by the Board will however continue to be known as Western Regional Production Development Board Scholarships and all recipients of awards will continue to be referred to as Western Regional Production Development Board Scholars.

2. In effect the Ministry of Education are acting only as agents for the Board in administering their scholarship awards. The terms and conditions of existing awards therefore will in no way be affected; and all scholarships awarded or to be awarded by the Board will continue to be regarded as quite separate from scholarships granted by the Western Regional Government.

(J. R. Boss)
for Permanent Secretary,
(Students Division)
Ministry of Education
Western Region.

No. 60.

## Claims Under the Bonn Conventions In Respect Of Foreign Interests In Germany.

(The English Text of the Conventions (Cmd. 9368) is obtainable from H.M.S.O. price 5s. 0d)

Under the provisions of Chapter 10 of the Bonn Convention on the Settlement of Matters Arising out of the War and the Occupation, United Nations nationals and companies organised under German law in which U.N. nationals own participation may assert claims against the Federal Republic of Germany for the return of their property and the restoration of their rights and interests in the Federal territory to the extent to which such property, rights or intrests suffered discriminatory treatment (as defined in the Convention) during the resent war.

Such claims must be filed on or before May 5 1956 with the:-

BUNDESAMT FUER DIE PRUEFUNG
AUSLAENDISCHER RUECKGABE UND
WIEDERHERSTELLUNGSANSPRUECHE,
ROSENBURG,
BONN,
WEST GERMANY.



# Enia Metadinlogun Ninu Igbe'kun

Fernando Po:- Irohin ti a nri gbọ lati ilu Fernando Po ri wipe awọn oṣiṣẹ enia mẹtadinlogun ni awọn agbanisiṣẹ da sinu ẹwọn laiko ba wọn ro'jọ lati gbọ ti ẹnu wọn.

Ni ọsẹ tokoja ni a gbọ wipe Ọgbẹni onişẹ iwe Irohin kan ti oruko rẹ njẹ J. T. Pepple nwọn fi s'ẹwọn laiko gbọ ti ẹnu rẹ ni Santa Isabel ti işe olu ilu Fernando Po, eyi ti a tun gbọ ni wipe Ọgbẹni Pepple yi kọwe lati inu ọgba ẹwọn ninu eyiti o fi han wipe awọn enia ara ilu Nigeria mẹtadinlogun ni awọn agbanisişẹ ko da s'ẹwọn laiko ba wọn ro'jọ gbọ ti ẹnu wọn.

KILO FA SABABI?

Ohun pataki ti Ọgbẹni Pepple sọ wipe o mu awọn agbanisişẹ na fi enia mẹtadinlogun wọnyi s'ẹwọn ni wipe nwọn gba awọn Minister mẹta lati i'ẹ wa nihin lalejo sinu ile apejẹ kan (Hotel) nilu Santa Isabel nigbati awọn Minister na lo bẹ ilu Fernando Po wo awọn alaşẹ ilu na ni ifura wipe awọn enia na le sọrọ aşiri fun awọn Minister na nibi apejẹ na, nitori eyi ni nwọn şe mu awọn enia mẹtadinlogun na ni ọjọ kejila oşu February ti nwọn si da si itim le ninu iyara kan to gun ni ẹsẹ mẹdogun to si fẹ ni ẹsẹ mẹsan.

Gbogbo awọn enia mẹtadinlogun na ara ilu Ibo ni wọn, (Eastern Region) orukọ wọn niwọnyi:- Michael Onochie, Jonathan Nwadiozo, Paelinus Ibe. John Iinwa, Obedia Nwagbara, Marcus Nwachuku, Nathaniel Azubike, Lawrence Eme, Alexander Metu, Benedict Adamekwe, Alfred Okoye, Michael Nwokoro, George Ukonu, Ezekiel Uduma, Bernard Uko, Joseph Uma ati Gabriel Eme

Ninu ọrọ Ọgbẹni Pepple yi ni a gbọ wipe o sọ pe on ti lọ si ilu Fernando Po yi l'ẹkan ri fun işẹ Iwe Irohin Ọsẹsẹ ti on nşe nilu Port-Harcourt, ki on to wa gba ọ'ọfẹ-ara lọ silu na, lẹhinti Ọba Obinrin pada sile tan, iyẹn jẹ ọjọ kinni oşu March, nigbati on si de ọhun, irohin ti on gbọ ni wipe agbanişẹ kan ti lu awọn oşişẹ rẹ meji ara ilu Nigeria ti oju wọn wu.

Lori irohin yi ni on fi lọ sọdọ ọga agbanişişẹ na, o si sọ fun on wipe otitọ ni ọrọ na, nitoripe wọn ko wa sibi işẹ fun ọjọ meji ni on şe lu wọn bẹ. Eyi ko jẹ itẹlọrun fun on ni on fi lọ fi ọrọ na han Aşoju Ijọba Gẹsi ati Alabojuto işẹ, wọn si dide si ọrọ na pẹlu Alabojuto Işẹ ti awọn agbanisişẹ (Spanish Labour Officer) Nitorina ni Ọga agbanisişẹ na şe fi ọlọpa mu on ni wipe on ko gbaşẹ lọdọ ọga Ọlọpa ki on to ma wadi ọrọ işẹ ati pe on bu awọn ara ilu FernandoPo, on si nşe ileri wipe on ko ni jẹ ki nwọn ri awọn enia Nigeria gba wa şişẹ ni Fernando Po mọ.

Eyiti on kan nilu Santa Isabel re o, olu ilu FernandoPo, labẹ ijọba awọn Spanish.

# Ile Iwe Ọmode Ni Ibadan

Ni ọjọ kẹrindinlogbọn oşu keta ọdun yi ni Olubadan I. B. Akinyẹle O. B. E. şi ile ikawe ẹkọta fun ọmọde ni Aperin Ibadan. Irinwo Pọun lo pari rẹ eyiyi lo si di ẹkẹrinla iru rẹ ti a si si Ipinlẹ Iwọ-Orun Ile ikawe yio wulo fun gbogbo ọmọ ile iwe to wa ni gbogbo agbegbe Arẹmọ ati Aperin


# Fi apa - iyẹ si mọto rẹ!




Mobiloil tuntun pataki yi njẹki ẹrọ rẹ şişẹ lọna iyanu--ni gbogbo orişirişi ọna--o dabi igbati o ba fi apa iyẹ si mọto ayọkẹlẹ rẹ ni! Epo mọto alailẹgbẹ yi le şişe bakanna nigba ẹrun tabi nigba otutu. Ki i jẹki ẹrọ yọnu tabi ki o kidanpapa rara--A ma mu ki ẹmi ẹrọ o gun ni ilọpo meji. Mobiloil tuntun pataki yi ki i jẹki ẹrọ tete bajẹ, a ma a mu ki gbogbo irinşẹ inu ẹrọ ma a şişẹ daradara-- fun eyi, ki i si mu ki ẹrọ jẹ epo, a ma a mu ki ẹrọ ma a sure işẹ pẹlu igbadun, a ma a mu ki ẹrọ lo epo diẹ fun ọpọlọpọ mẹili. Lo Mobiloil tuntun pataki yi wo fun iyatọ ti wa a ri i ni ẹsẹ-ayika-kẹkẹ!

NEW
Mobiloil
SPECIAL

O dara fun awọn ogbologbo mọto -- ọranyan si ni fun awọn mọto titun!

Mobil Oil Nigeria Limited

## Ipade awon Lemomu Nilu Ibadan

Ninu pade ti awọn Lemọmu Aşiwaju Ima'e şe nilu Ibadan fun ọjọ meji, awọn şe ip'nnu wipe awọn yio fi ọrọ ọba Alafin Ọyọ siwaju igb'mọ alabajiroro ti Gomina Iwo-orun (West Privy Council) fun agbayẹwo to şẹlẹ nilu Ọyọ ni ọjọ Karun oşu September t I ọdun kẹta s'ẹhin, awọn Lemọmu pinnu lati bẹ igbimọ Gomina ki nwọn o maşe gbọ ti awọn enia ti o wi pe ki nwọn yọ Alafin na patapata.

OBA ALAFIN OYO



Alhaji Aderiran Adeyẹmi

Ẹnyin ọkawe wa yio ranti wipe Ọba Alafin, Alhaji Aderiran Adeyẹmi Keji yi ni ijọba Iwọ-orun mu lọ si Ilesha lasiko rogbodiyan ija

## Jamba Oko Omi L'ona Ajase

Agbọ ju'gbanu ni irohin ti agbọ nipa ọkọ oju omi kan ti o ko awọn enia nlọ si Ilu Ajaşẹ (Badagry) wipe jamba şe ọkọ na, o sojude sinu omi. A koiti gbọ bi nkanna ti şẹlẹ ati awọn enia ti jamba na şe.

Lọwọ iku ına, iku omi Oluwa rere, gbawa!

## Alo o Alo!

Ọkọ ni ọkọ Obembele, isa ni isa Omukẹ-mukẹ, Ọkọ Obembele ko le ya bẹni isa Omukẹ-mukẹ ko le pin.

Tani le ja alọ yi?




A GIFT FROM HEAVEN!

BAMWO BABY MIXTURE

OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.

PRICE: 2/6 POSTAGE 1/

THE EGBA TRADING ARADAN STORES. 144 DENTON STREET, P.O. Box 2, EBUTE METTA & BRANCHES



## Enjoy Your Own --- Songs ---

Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC :- yours, on obtainable from is

The Association Of Nigeria Gramophone Dealers . . . . THROUGHOUT . . . . . . . . . NIGERIA . . .



Bi egbogi Koko oni - "Four Oaks"

ti şe ngmu KOKO DARA ti o si ngmu ki awọn Agbẹ Naijiria JERE PUPỌJU

- Ki i jẹ ki nwọn PADANU nipa pipa gbo-gbo arun ara igi ati ti eso Koko
- A maa mu Koko GBILẸ si pupọ l'oko
- A tubọ ma jẹki Koko ni IYE lari
- AGBARA rẹ ni ifọkanbalẹ, atunşe ati abo



A o ri awọn egbogi koko oni - "FOUR OAKS" yi lọdọ Ẹgbẹ Onişowo Co-operative Supply Association tabi Onişowo Co-operative Produce Marketing Association ni ofisi tabi ni ile itaja wọn. Gbo-gbo irin ara ẹrọ na ni o wa lọtọọtọ fun tita.

COOP WESTERN NIGERIA


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23378